Ẹ jẹ́ iṣẹ mi koda bo ṣe pẹlu aayah kan, kí ẹ sì sọrọ nipa àwọn ọmọ Ísírẹ́lì, kò sí aburu nibẹ, ṣugbọn ẹnikẹ́ni tí ó bá mọ́ọ́mọ́ parọ́ mọ́ mi, kí onitọhun yaa tètè mú ibùjókòó rẹ nínú Iná

Lati ọdọ Abdullah ọmọ ‘Amr - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji - ó ní dajudaju Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pé: "Ẹ jẹ́ iṣẹ mi koda bo ṣe pẹlu aayah kan, kí ẹ sì sọrọ nipa àwọn ọmọ Ísírẹ́lì, kò sí aburu nibẹ, ṣugbọn ẹnikẹ́ni tí ó bá mọ́ọ́mọ́ parọ́ mọ́ mi, kí onitọhun yaa tètè mú ibùjókòó rẹ nínú Iná".

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlohun maa ba a - n pàṣẹ pé ki a gbé ìmọ̀ oun kaakiri, yala o jẹ lati inu Al-Qur’an ni tabi lati inu Sunna, koda ki nkan naa jẹ kekere gẹgẹ bii aayah kan pere lati inu Al-Qur’an tabi Hadiisi kan pere, pẹlu majẹmu pé ki olujiṣẹ naa jẹ́ onimimọ nipa nkan ti ó fẹ́ jiṣẹ rẹ, tí ó sì fẹ́ kéde rẹ. Lẹyin naa ni Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ṣalaye pé ko si aburu pẹlu sisọrọ nipa awọn ọmọ Ísírẹ́lì, ati nipa awọn ìsẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹlẹ̀ sí wọn, pẹlu pé kó ṣá ti má tako ofin sharia tiwa. Lẹyin naa, ó wá wa ní isọra kuro nibi píparọ́ mọ́ òun, nitori pé ẹnikẹni tí ó bá mọ́ọ́mọ́ parọ mọ oun, kí ó yaa tètè gba aaye kalẹ fun ara rẹ ninu ina.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3686